**Wanted Urgently**

1 Advanced Apprentice and 1 Apprentice Printers
Apply to
Modupẹ Printing Press
16, Bamghose St. Lag
Phone: 21985

# IRỌHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**AKIYESI**

Ki ẹnikẹni ti oba fẹ ra Iwe Irohin Imọlẹ ni Abeokuta ma lọ ra lọdọ Asoju wa
Ọgbẹni Francis Ogundimu
6, Ake Street,
Abẹokuta.

VOL. III No. 126 MONDAY NOVEMBER 30 — DECEMBER 6 1959 KỌBỌ KAN (1d)

# Ijoba Ila-Orun pe olori Alatako lejo

ABA Oloye Sam Ikoku Olori Alatako ni ile igbimọ Ila Orun nihin ni o fi ara han ni ile ẹjọ, ti a si fi ẹsun sun pe o tapa si Ijọba ni ọrọ iwe waya (Telegram) ti o te ransẹ si Olotu Ipinlẹ na Dọkita Nnamdi Azikiwe ninu oṣu kejọ ọdun yi (August) ti o si sọ fun pe ki o yọ eto ti o wa fun awọn oloye igbakeji (Second Class Chief) ti wọn lọ si Igbimọ awọn oloye ti a fẹ da silẹ ni Ipinlẹ Ila Orun.

Ninu waya rẹ, Oloye Ikoku tọka si wipe eto ti ijọba Ila Orun ṣe nipa ọrọ awọn oloye na ba iṣesi ati iṣẹdalẹ awọn enia ipinlẹ na, ati wipe bi a ba gbe eto na dori, gbogbo awọn oloye ni yio tako-o. Ninu waya kan yi ni oloye Ikoku gba Dọkita Azikiwe ni imọran pe ki o kuku pa eto na rẹ. Dọkita Azikiwe si ti pa eto na mọ, ko si ti gbe jade.

Niwaju adajọ Phil Ẹbosie ni Oloye Ikoku ti sọ wipe on ko jẹbi ẹsun na, ti a fi sun on pe on tapa si Ijọba Ninu iwe ẹjọ awọn ọlọpa ni wọn sọ wipe waya Oloye Ikoku yi n'kin awọn ti ko ni tẹrun si Ijọba, osi ṣe si ofin ni abẹ ofin Ipinlẹ. Ile ẹjọ gba iduro oloye Ikoku fun Ọgọrun Pọun ati oniduro kan Ẹjọ na yio bẹrẹ ni oni oniwe irohin wa kan fi ye wa pe ọpọlọpọ awọn amofin ti Action Group ni yio rojọ Oloye Ikoku.

## Eniti won fe dibo fun, lo si EWON

Thomas Nochiri Nwoko ẹni ti o jẹ ọmọ Ogoji ọdun o le meta ni adajọ ti ile ẹjọ ni Eko kan ju si ẹwọn ọdun meji, nitoripe o yi iwe Ibo a ti pe orukọ ti o ko silẹ ki iṣe tirẹ. Lẹhin igbati ati mu Nwoko lori ẹsun yi ni alatako rẹ Ọgbẹni Oliver Biaduo ni o wọle ni rọwọ rẹ sẹ. Agbẹjọ ro Ọgbeni I. S. Adewale ti o pe ara rẹ ni ọrẹ ile-ẹjọ bẹbẹ fun anu pe ki a da Ọgbẹni Nwoko silẹ. Ninu idajọ rẹ Adajọ Victor E. Creine, sọ pe o jẹ ohun ti o ru on loju lati ri wipe Nwoko sẹ ọrọ ẹsun ti a fi sun, atipe on ko ṣe iyemeji pe ki i se Nwoko lo yi iwe Ibo na, si oruko Sunday Nwoko ọkan ninu awọn eleri Ijọba.

O sọ wipe ọdaran, yi mọ pe orukọ ti a kọ ti a kọ si iwe Idibo pe lagbaja duro fun lakaṣegbe ki i ṣe orukọ ẹniti o ṣo wipe o duro fun on, ati wipe nigba ti a ti fun odaran yi ni o aye pe ki o se ibere lọwọ awọn ẹlẹri ni o wa fiban gbagba pe, o sọ ọrọ mọ ara rẹ lẹsẹ nitori na otọ ọrọ nipe o yi iwe.

Ni ipari Adajọ sọ wipe, Ẹbẹ fun anu ni o jẹ ki o dabi ẹnipe okan on fẹ tutu, ṣugbọn sibẹ ni o jẹ ọniya. Iya rẹ yio jẹ apẹrẹ fun awọn ẹlomiran ti o nba gbaro lati da ẹṣẹ ti o fẹ da yi.

## Ha! eti re melo?



Eyi yi ni Ẹrọ Alata todaraju gbogbo eyi ti wọn ti nlo tẹlẹrilọ lẹyin ata lilọ o tun le lọ Igbado ati Ọka Baba ati Ẹwa - ere orisirisi.

**£45 Ni a nta** Pẹlu Enjinni Pẹtrol tabi ati pẹlu Ẹlẹtiriki Mutọ.

O WA NI SỌBU:-

**Akoshile Brothers,**
5, Balogun street West,
P. O. Box 599.
Phone No., 24395. LAGOS.

## MOGBAYI BABY MIXTURE

OLURANLỌWỌ FUN AWỌN ABIYAMỌ




MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ ogun pataki ta ṣe ni Aṣepe fun Awọn ọmọde, ati nlo ogun yi fun ẹpọlọpọ ọdun sẹhin pẹlu idaniloja fun Awọn iṣẹ ribiribi ti ó ti nṣe. MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi to dara pupọ fun igbona ikọ, otutu Aiperi, Osi inu ọmọde, jẹdi jẹdi Kokoro ori ọmọde. O dara fun ọmọde ti ko tete rin ati fun awọn aisan miran bẹbẹ lọ. O nmu ki ọmọde ma nsun fọnfọn, o nmu ki ehin hibu jẹ irọ run fun awọn ọmọde, osi njẹki awọn ọmọde tobi, osi nmu wọn dan ni awọ Ẹnyin Abiyamọ, ẹku afojuba egbogi yi. Aran yin leti pe MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi ti ko ṣe mani fun awọn ọmọde. Ijafara lewu pupọ, tete lọ ra ti e ni ile itaja Egbogi towa ni Adugbo rẹ.

Igo kekere rẹ jẹ 2/6d Igo nla jẹ 4/6d
**LILO RE:-** Sibi kekere kan lẹmeta lojumo

*Wholesale Distributers*
**A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHERS**

| | |
|---|---|
| 6, Balogun Street West | 34, Docemo Street |
| Lagos Nigeria. | Lagos. |
| Phone 22515 | Phone 24247 |

# IMOLE

E.IN OKO WA:
IMOLE DE OKUNKUN PARADA

*Editorial Works & Office*
16, Bamgbose Street, Lagos.
Telephone: 21985
United Kingdom Representative
Publishing Distributing
177, Regent Street,


## IBEWO OLOTU IJOBA GEESI

Ikede ti o jade pe Olotu Ijoba ile Gesi Ologla Harold Macmillan yiose abewo wa si ile wa ni osu kini odun 1960 (January) dun mo wa ninu pupo.

Lona kini ti o fi dun mo wa ninu ni pe yio be ile Najiria yi wo ni odun ti Ijoba re so wipe won yio fun wa ni Ominira.

Ona keji ewe ni pe rogbodiyan a o dibo wole ti awon Egbe Oselu nse nisiniyi yio ti kase nile, atipe Ijoba ti yio se enu Naijira ti a ba gba Ominira ni yio ba.

Sugbon ejo ki a ye oro kan wo, lati igba ti Ijoba Gesi ti fi ese mule ni ile wa yi ko ni tabi-tabi kan a bi kele-kele kan lokan lati ri pe won ni ese wa lorun ati pe awon papa ko le ri esun kan sun wa, sugbon nkan ti Ijoba Gesi nse fun awon omo iya wa ni ile ila Orun ti Afrika ko te wa lorun gegebi enia dudu, iya ti ko se fi enu so ti won fi nje won po otito ni ti a ba so wipe ti Ijoba Gesi ba fe ki ore ti o wa larin ile wa pelu ti won nisinyi yi ki o wa ja pe ki won wo ti awon omo iya wa yi se.

Okun ore ti o wa larin wa pelu Gesi lopo to be ti ko nise ja boro; sugbon ko je didun inu wa lati ri pe iya kiya kan nje awon omo enia dudu nibikibi ti won ba wa ati pelu-pelu awon ti o wa ni abe asia Gesi.

Ao fi inu didun ati to kan-tokan gba o Mac. to ba de bi ni osu kini odun to mbo (January) a si so o-pe okun ore ti o lopo ti o wa larin ilu yi pelu ilu re yio si fun di gbayingbanyin lehin igbati o ba se abewo re tan.

## Elewon kan tu lori ide, o si saluko

ABA. Awon olopa ti beresi se ode okunrin elewon kan ti oruko re nje Nathan Odinkemere ti o puro wipe oti gba oye ninu ise Oluko, ti o si fi oye na ti ko gba rara ugba owo geregere.

Ninu ogba ewon ti Eko ni o gbe wa ti o nse ewon re, sugbon ijoba fe mu lo si ibomiran ki o le lo se ewon re nibe. Nibiti awon olopa gbe imulo, ibe ni okun idi re ti ja, lo ba sa lu igbe ti o si di awati.

Awon olopa si nse ode re lowo, nwon ko si ti mo ibiti o gbe wa.


## Iwe Ilana Ifa, Erindinlogun, Iyanrin tite, Iwosan ati etutu sise pelu Egbogi Ajebidan

Ha! eti re melo? Ogbokangi Babalwo ni o sese se iwe yi fun tita ati fun anfani gbogbo enia, ohun ti o wa ninu iwe yi ni (1) Ayajo ti o daju hanraun, (2) Yanrin tite, (3) Egbogi Ajebidan, (4) Eyonu awon agba (5) Awure wibe, jebe, (6) Etutu iwase Ajebidan, (7) Ojulowo iwe Ifa ni ise. Babalawo tabi awon ti o ba fe ko Ifa nilati ni Iwe yi lowo, bi o ba ni iwe yi lowo, awon Ota, Eleiye, Alapeta, Apeniapa, Adahunse Ologun, Babalawo ati awon enia majeki teni sunwon ko ni lagbara lori re.

IYE OWO

10/6d eyo kan, £3 mefa, £5 : 0/- Dosini.

### Turari Ajebidan

Turari yi tun lagbara bakanna lori awon Eleiye, nipa lilo re, o ko ni [illegible] tita oja, agbana ko si ni wo inu igba re, o le lo fun adura Tetedamilobun, Ako jafugbe ni fun awon Emi okunkun, ni kukuru, Gbogbonse ni Turari yi, danwo

IYE OWO

10/6d Pangolo, 5/6d Idaji 3/- Idamerin 1/- Idarun

Iwe Itumo Ala 2/6d, Gbedegbeyo Hausa 2/6d, Certificate of service 5/6d eyo kan.

FI OWO RANSE SI:- J. O. SHOYINKA, 6, Ojo Road, Oduabore Mushin.


## ÈTÒ ÈKÓ ÀWỌN ÀGBÀ



Èto eko ti Ijoba Ipinle Iwo Orun se fun awon agba, l'okunrin l'obinrin, ti ko ko eko tan ni ile-eko kekere tabi ti kotile ko rara, l'aye lati se atunse nipa eko won. Ijoba nse iranlowo fun won lati le ka ati lati ko iwe ni ede ti won ki nwon bale se ipa ti won daradara ninu ise itesiwaju ti isela ati ti igbadun awon enia. Ijoba ti pese owo fun awon osise ti nmu ojuto eto eko yi fun tite ati pinpin awon iwe Yoruba ati ti ede [illegible] fun kika. Ijoba Ipinle tun nfun awon Ijoba Ibile ni owo osu ti nwon nsan fun awon ti nse eto eko awon agba ti Ogu Ile Ise eto eko ti fi ase si gbigba won. Ijoba si nse iranlowo bakanna fun Ile Ika'we ni Ileto ati fun iwe irohin nibe.

Owo ti Ijoba fi sile fun ise eko awon agba ni odun 1955 si 1956 je edegbafa poun, ti 1956 si 1957 je egbaaa poun o le egbesan ati ogun. Iye kanna ni Ijoba na ninu odun 1957 si 1958.

Larin odun meta ti o koja awon agba to f'oruko sile fun eko yi je oke marun o le e [illegible] ati odunrun o din metadilogun—ni odun 1955 awon ti nwon fi oruko sile je edegbafa ni odun 195[illegible] oke meji abo, ni odun 1957 oke meji o le edegbeje o din medogun.

Ile Ise ti nkede Ise Ijoba Iwo Orun Naijiria l'ogbe oro yi jade.

# Itumo ALA awon onibere

JOSEPH AJALA ERUṢU OKE IGA AKOKO DISTRICK:—Bi o ba jẹ gbẹnnagbẹuna tabi ẹniti o nfi Ogun ṣiṣẹ ṣọra gidigidi lasiko yi ki o ma ba ri ifarapa bi o ba jẹ Onigbogbo jọwọ kun fun adura lojojumọ, ti ọ ba si jẹ Aborisa, tete yara lọ bọ ogun o.

O le bere Itumọ Ala tirẹ papa lọwọ JOSEPH Alala 6, Ojo Road, Odu Aborẹ MUSHIN.

## KERE O, AKIYESI PATAKI

'Awa na le jeri wipe ojulowo baunhaun Egbogi gidi ni LEOPILLS', Awa na si nlo ni ilu wa Gold Coast (Ankara) Ghana pẹlu, meji rẹ kosi ninu gbogbo oriṣiriṣi Egbogi kakiri ilu Naijiria.




## Irohin Kakiri Igboro ilu Eko

Bẹna si ni ẹwẹ ni igboro ilu Eko, irohin ti o wa lenu gbogbo enia, ti ọmọde ti agba ni asiko yi ti wọn si nfi ṣe ọrọ ati orin kọ larin ara wọn jẹ nipa ti egbogi Jamani olokiki yi ti wọn npe ni 'Leopills'

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti won ṣe iwadi Egbogi LEOPILLS yi kan sọ wipe Bi o ti Lagbara to, ti o jẹ ojulowo giriki ati atamatase fun iwosan JEDIJEDI bi o ti wun ki ọjọ rẹ ti le pẹ to, bẹna si ni awọn tun le fi ọwọ sọ aya tabi ṣe ileri fun gbogbo awọn ti amodi tabi aisan bi Akọ Inarun, Lakuregbe, Ejẹ dudu lara, Arun Edọki, Iju, Igbesise tabi Aikori Igbọnsẹ dede, Inu-rirun nigbakugba, Ara-wiwo, Esanri, Ehin-didun, Oju-sisu tabi aiko riran kedere, Kokoro buruku lara, Oṣi inu, Onigbameji, ati orisirisi arun ara miran, gbogbo pẹlu 'WIPE' wọn yio ri alafia ni kiakia bi wọn ba nlo egbogi 'LEOPILLS' nitoripe asi ma tun ẹjẹ ṣe lara enia nipa sisọ di ọtun patapata

ṢE IRANTI PE ALAFIA NI OGUN ỌRỌ
IJAFARA SI LEWU PẸLU O (POSTAGE 1/9d)
Egbogi Leopills:- Igo nla Ṣile-mẹfa pere ni
Igo Kekere:- Ṣile-mẹta abọ pere ni.

Bere ojulowo Egbogi omiran fun oriṣiriṣi amodi ti o ba fẹ ni ṣọbu awọn:—

Waterloo Medicine Stores
8. PalmChurch Street P. O.Box 333
Lagos Nigeria Phone 22878

Ati Pelu Ni Sobu Arabinrin:-

MRS. C. O. BABAJIDE,
NEAR HEALTH OFFICE IBADAN.

ati ni ABIMBỌLA MEDICINE STORES
B29 Okesha Street Ilesha

AKIYESI:— Ri daju gbangba wipe ṣọbu ti wọn nta lo gbe ranṣẹ lọra, bi bẹkọ awọn ẹlomiran yio ti ERU lọta adamọdi tabi oriṣi omiran fun ọ o, maṣe gba rara.

NJẸ O NI
OTUTU IBA










DỌKITA SỌ WIPE




Da OTUTU IBA rẹ duro
gbe koro "ASPRO" meji mi
ARA RẸ YIO SI TUN YA-GAGA

# TANIMEHINOLA APA 47

Lati Owo: J. O. SHOYINKA (Mushin)

Lẹhin ti Enmọ ti gba lelẹ araga tan, ti oju rẹ si ti pa kannakana, Enmọ bere lọwọ rẹ, o ni kini o wa dehin ? Tanimẹhinọla si dalohun bayi pe, nko ṣadede dehin, awọn ọmọ mi ti o ti ku ni mo nwa lọ, ki nto ṣi ọna gba, mo ti dide ni ile, ọjọ ti pẹ, ko si ilu ti ngo fẹsẹ mi bembe yi tẹ labẹ ọrun mo wa iku titi ba pade kaka ki nba iku pade, Iya ati Iṣẹ ni a jọ nfaiyalu aiya ni gbagbogbo.

Aiya Enmọ ja, o ni iku tabi kinla ? O nwa iku, Tanimẹhinọla ni bẹni on wi o tun bere lẹẹkeji. Tamẹhinọla tun ni mo nwa iku lojumejeji.

ENGMỌ BERẸSI SORỌ

Enmọ berẹsi sọrọ, o ni Tanimẹhinọla wolẹ. ki o wo ọrun, ngo han ọ ni babanla ENMỌ loni, lẹhin eyi, nko ro pe o tun le ṣe ọjọ meje lori ilẹ aiye yi, nitoripe nigbati ọwọ mi ba tẹ ọ tan dada, ọwọ Ọlọrun paapa yio kuro lara rẹ. Ki o to sọ bayi tan, awọn ọmọ eriwo ti so Tanimẹhinọla rọ bi ẹran ogunfe, o nrọ dirodiro. koi ti to iṣẹju marun lori iso ti o fi nlagun bẹrẹbẹrẹ o bẹrẹsi kigbe irora, sugbọn Enmọ ko dahun. Isan yi ko ni kun to, ko si ni dun to ti nko ba ṣe alaye bi Enmọ ti ri.

Enmọ jẹ enia kangitakangita, o sepọn ninu ati idi bi akọ Elẹde, agbari rẹ ri fọrẹgẹdẹ bi atẹ ọra, bi o ba ti nrin ni oju rẹ ma nran mọ-ọ mọ bi ina moto, Engmọ Frerin a fi ti o ba nsukun, ti o ba fẹ ru pako larọ eyi ti o fi ma fi pada de emi akọ yangi ni ma run gẹgẹbi orin, ẹnu rẹ a si ma sẹjẹ woru-woru ti o ba si yọ lokankan akojalugbe ni wọn a ma sọ pe Enmọ de ! Enmọ ! de nigbati ara Enmọ pa kọ, ni o fi gba aginju lọ ni kukuru, ẹnyin Onkawe mi Ọlọrun majẹki ẹ pade Enmọ o.

Nigbati Enmọ ri pe o jẹ aporo dada, o ni ki wọn fun tinu tẹnin, kini awọn jagunlabi nwa tẹlẹtẹlẹ, wọn na ni anapamoku, nigbati wọn ri pe ẹkọ kan ni o nmi wọn tu lori iso, olukulaku wọn tadi mẹhin wọn berẹsi woye, nigbati o to wakati marun ni Tanimẹhinọla taji wuye o wo rairai, ri awọn ọmọ riwo niwaju, ori rẹ yi o fi ibinu dide fus , gbogbo wọn ọ, o wa berẹsi fi ibinu sọrọ.

Akiyesi:— Lọsẹ ti o nbọ ẹ o ma gbo ọrọ ti o sọ ati bi on ati ENMỌ ṣe ja iji gbigbona, Tanimẹhinọla lo ọfọ ata lọjọ na o si ṣegun ENMỌ.

---

## Omupo Muslim Society

c/o General Secretary
5, AGOṢHỌFIN STREET
LAGOS 24:11:59

Gbami laye lati ṣe Ikede yi fun gbogbo agbaiye, ati fun gbogbo awọn tio bani Ifẹ Anabi Muhammed lati wagbọ "WAKA" ti Alufa Dodo-Oniwaka ti Ilu Ilọrin ati awọn ijọ rẹ yio waṣe ni Glover Memorial Hall ni ọjọ kẹfa oṣu kejila ọdun yi 6th Dec. 1959 fun Ẹgbẹ ti orukọ rẹ wa ni oke iwe yi.

Idipataki ti afi fẹ ṣe waka yi ni wipe nipa Ile Kewu Makarata, Muslim School ti a nkọ fun ilọsiwaju ẹsin Islamiyyah ni ilu Omupo.

Tikiti ti ao mafi wọ ile ni ọjọ na 5/- 2/6 ẹori Tikẹti na ra ni ọdọ Ogbeni Sulemana Mustapha, ni Nọ 156 Akanni st, L. E. D. B Shop, ati ni ọdọ Alhaji A. B. Lawal 6, Masalasi St. Oko-awo Ọlọrun ko jẹ ka ro ju kara ye.

Modupẹ pupọ fun aiye ti ẹfi gba mi.

Emi ni-:
Alufa A. B. Bakare Tijani

---

Printed and Published by MODUPẸ PRINTING PRESS 16, Bamgboṣe Street, Lagos Phone: 21985. Olotu E. A. Adeniji 51 Tojuoṣho Street Sura Lere YABA
FUN OWO "IROHIN IMỌLẸ" ỌDUN KAN EKO— Ṣile Mẹrin ati Kọbọ Mẹrin (4/4d) ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun, Ṣile Mẹfa ati Kọbọ Mẹfa (6/6d)

ṢỌRA FUN

OTUTU IBA










DỌKITA SỌ WIPE




Da OTUTU IBA rẹ duro
gbe koro "ASPRO" meji mi
ARA RẸ YIO SI TUN YA-GAGA